# Ogun Ọ̀daràn àti Ìtòrò Àwùjọ nínú Àṣàyàn Ìwé Ìtàn-Àròsọ Yorùbá

*Arówóṣẹgbẹ́, Deborah Bámidélé* (*PhD*)

## Àṣamọ̀

*A ṣe àkíyèsí pé ọ̀pọ̀ ogun tí ó ń wáyé láàrin ìlú sí ìlú, ẹ̀yà sí ẹ̀yà, orílẹ̀-èdè sí orílẹ̀-èdè ti ń dínkù lónìí ṣùgbọ́n àwọn ọ̀daràn tó ń kó ogun ja ìlú ṣì wà síbẹ̀; ogun yìí sì ń gbẹ̀rẹ̀gẹ̀jigẹ̀ láwùjọ ọmọ ènìyàn lójoojúmọ́. Ọ̀gọ̀ọ̀rọ̀ ẹ̀mí àti dúkìá ló ń bá àwọn ogun náà lọ. Àwọn òǹkọ̀wé Yorùbá a máa pe àkíyèsí sí oríṣìíríṣìí ogun tí àwọn ọ̀daràn ń gbé ti àwùjọ. Ète àtimọ ìhà tí òǹkọ̀wé ìtàn-àròsọ Yorùbá kọ sí ogun ọ̀daràn yìí ló mú kí a ṣe àyẹ̀wò ìwé ìtàn-àròsọ Yorùbá méjì; Oorun Orí Kẹ̀kẹ́ àti Oko Aga tí Olúmúyìwá (2008, 2012) kọ. Yíyan ìwé méjì tí òǹkọ̀wé kan ṣoṣo kọ yóò fún wa ní àǹfààní láti walẹ̀ jìn léte àti mọ ìhà tí òǹkọ̀wé náà kọ sí ọ̀ràn dídá. Ète iṣẹ́ yìí ni láti fi Olúmúyìwá hàn gẹ́gẹ́ bí òǹkọ̀wé ìtàn-àròsọ ajẹmọ́-ọ̀ràn dídá. Tíọ́rì ìfojú-ìmọ̀-ìbára-ẹni-gbé-pọ̀ tó gba lítíréṣọ̀ gẹ́gẹ́ bí aṣàwòjíji àwùjọ ni a gùn lé fún iṣẹ́ ìtúpalẹ̀ náà. Tíọ́rì yìí gbàgbọ́ pé ohun tó ń ṣẹlẹ̀ láwùjọ ni àwọn òǹkọ̀wé ń túfọ̀ nínú iṣẹ́ àtinúdá wọn. Àbájáde iṣẹ́ yìí fi hàn pé oríṣìíríṣìí ogun ọ̀daràn bí i ìjínigbé, ìdigunjalè, ìfinisètùtù, ìfipábánilòpọ̀, àti àwọn mìíràn tó ń fa àìbalẹ̀-ọkàn ló kún àwùjọ. Lára ohun tí òǹkọ̀wé fúnka mọ́ pé ó ń fa ogun ọ̀ràn dídá wọ̀nyí ni àìsíṣẹ́ fáwọn ọ̀dọ́, àìní ìtọ́jú láti ọ̀dọ̀ òbí, ẹgbẹ́ kíkó àti àìṣe mọ́ríyá fáwọn ọlọ́pàá. Òǹkọ̀wé dábàá pípèsè ohun-èlò ìgbàlódé fáwọn ọlọ́pàá àti níní ìfẹ́ ìlú ẹni lọ́kàn gẹ́gẹ́ bí ọ̀nà láti dín ogun ọ̀ràn dídá kù láwùjọ.*

*Kókó-Ọ̀rọ̀:* *Ìbọn, Ìdigunjalè, Ilé-ìfowópamọ́, Ọlọ́pàá, Ọ̀ràn Dídá.*

## Ìfáárà

Ìfẹ́ láti di Akin ènìyàn, láti di aláṣẹ láàrin ìlú, láti wà ní ipò gíga, láti wá iyì àti ogo orílẹ̀-èdè ẹni, láti jà gba ara ẹni tàbí ènìyàn ẹni sílẹ̀ mú kí àwọn Yorùbá máa lo gbogbo agbára wọn láti jà lójú ogun. Ìwúrí àti ògo ni fún ọmọ Yorùbá láti ja àjà-ṣẹ́gun. Àwọn ọdẹ ní í má í jagun láyé àtijọ. Bí ogun bá parí púpọ̀ wọn a padà sí ibi iṣẹ́ wọn. Òríṣìíríṣìí ètò ogun jíjà bí Ifá dídá, ìpolongo láàrin ìlú, ètò ìpabùdó, ríró èso igi àti ohun-jíjẹ, sísé ọtá mọ́lé, rírán iṣẹ́ ohùn, wíwọ̀lú ló-jiji àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ ni Yorùbá ń lò (Adéoyè 1979:295-299). Wọn a sí máa lo àwọn ohun ìjà bí òkò, kùmọ̀, àdá, ọfà, àkàtàǹpó, ìbọn ṣakabùlà àti oògùn. Ọgbọ́n àti ète ńlá ni àwọn baba ńlá wa máa ń lò lásìkò tí wọ́n bá ń múra ogun tàbí tí wọ́n bá wà lójú ogun. Lára ohun tí Adéoyè (1979) sọ pé ó ń fa ogun ni sùnmọ̀mí gbígbé, ẹ̀mí ìlara àti ìrẹ́jẹ, ìjà ààlà ilẹ̀, ìjà fún igi owó, ojúṣe Ààrẹ gẹ́gẹ́ bí ipò rẹ̀, gbígbéjà ìlú tí a nífẹ̀ẹ́ sí, bí Aláàfin tàbí Ọba aládé tàbí Ààrẹ Ọ̀nà-kakaǹfò bá fẹ́ yẹjú akíkanjú tàbí olóríkunkun ìjòyè, láti wá ìlú amọ́nà kúnra, láti fi jagunja-

gun hàn bí olókìkí, olóogun tàbí akọni àti láti kó owó àti dúkìá jọ. Bí ogun bá gbóná gidigidi tán, òfò àti àdánù tó ń ṣe ìlú máa ń pọ̀ lápọ̀jù; ìlú a máa tú, ẹ̀mí àti dúkìá a máa ṣòfò, ìyá kò níí mọ ibi tí ọmọ yà sí; ọ̀pọ̀ ènìyàn ni wọ́n máa ń pa ní àpasáyé, oko a di ìgbẹ́; ilé a dahoro, ìlú yóò sì di igbó.

Lóde-òní, kò sí ibi tí irúfẹ́ ogun tí a mẹ́nu bà yìí ti ń wáyé mọ́ nílẹ̀ Yorùbá. Àwọn ènìyàn tètè máa ń dìde láti paná ìjà bí wọ́n ba kẹ́fin pé ìjà náà lè di ogun. Síbẹ̀, àwùjọ kò yé ogun í jà. Ọ̀nà tí àwùjọ ń gbà ja ogun àti irúfẹ́ ogun tí ó ń jà ló yàtọ̀ díẹ̀ sí àwọn tí a ti ṣàlàyé ṣáájú. Ọ̀kan lára ogun tó dojú kọ àwùjọ lónìí ni ogun ọ̀ràn dídá tí àwọn ọ̀daràn gbé ti àwùjọ. A ṣe àkíyèsí pé ètò irúfẹ́ ogun yìí yàtọ̀ sí èyí tí Adéoyè (1979) àti Dáramọ́lá àti Jéjé (2005:143-145) mẹ́nu bà. Àwọn ènìyàn mọ àwọn jagunjagun tí Àdéoyè àti Dáramọ́lá àti Jéjé mẹ́nu bà ṣùgbọ́n ní ọ̀pọ̀ ìgbà, ṣe ni àwọn jagunjagun ọ̀daràn wọnyí máa ń farasin bẹ́ẹ̀ ni kò sí àlàkalẹ̀ pàtó tí wọ́n ń tẹ̀lé láti ja ogun wọn. Àwọn òǹkọ̀wé ìtàn-àrosọ kò yé pe àkíyèsí àwùjọ sí ọṣẹ́ tí ọ̀ràn dídá ń ṣe ní àwùjọ, okùnfà ọ̀ràn dídá, bẹ́ẹ̀ ni wọn a sì máa dábàá àwọn ohun tí àwùjọ lè ṣe láti mú kí ogun ọ̀ràn dídá dínkù láwùjọ. Nínú iṣẹ́ yìí, a ó wo ìhà tí Olúmúyìwá (2008, 2012) kọ sí ogun ọ̀ràn dídá tí ó ń ja àwùjọ gẹ́gẹ́ bí ó ṣe hàn nínú àwọn ìwé ìtàn-àròsọ *Oorun Orí Kẹ̀kẹ́* (*Oorun*) àti *Oko Aga* (*Oko*) tí ó kọ. A yan ìwé méjèèjì tí òǹkọ̀wé kan náà kọ láàyò láti lè walẹ̀ jìn lórí ìhà tí òǹkọ̀wé alátinúdá náà kọ sí ọ̀ràn dídá ní àwùjọ léte àtifìdí rẹ́ múlẹ̀ pé òǹkọ̀wé ìtàn-àrosọ ajẹmọ́-ọ̀ràn dídá ni Olúmúyìwá.

## Tíọ́rì Àmúlò

Tíọ́rì ìbára-ẹni-gbé-pọ̀ láwùjọ èyí tí ó gba lítíréṣọ̀ gẹ́gẹ̀ bì ìṣàwòjíji àwujọ ni a fi ṣàtẹ̀gùn fún iṣẹ́ yìí.

### Tíọ́rì ìbára-ẹni-gbé-pọ̀ láwùjọ̀

Òpìtàn ará Faransé tí ó ń jẹ́ Hippolyte Taine ló gbajúmọ̀ jù lọ̀ lára àwọn agbátẹrù ìlànà yìí gẹ́gẹ́ bí Ọ̀pẹ́fèyítìmì (2014:51) ti sọ. Tíọ́rì ìbára-ẹni-gbé-pọ̀ láwùjọ gbàgbọ́ pé àwùjọ àti lítíréṣọ̀ kò ṣe é yà sọ́tọ̀ síra wọn. Ògúnṣínà (1988:85) fi hàn pé àfihàn àwùjọ ní lítíréṣọ̀ jẹ́. O rí lítíréṣọ̀ gẹ́gẹ́ bí afìpin-ojú ẹni-han-ni a sì máa ṣe àtúpalẹ̀ àwùjọ. Ìgbàgbọ́ àwọn tó ń lo tíọ́rì yìí ni pé èso àwùjọ ni lítíréṣọ̀ jẹ́. Inú àwùjọ ni oníṣẹ́-ọnà ti ṣa àwọn èròjà tí ó lò jọ. Àwòjíji àwùjọ ni lítíréṣọ̀ ń ṣe. Gẹ́gẹ́ bí Adèbọ̀wálé (2003:2) ti sọ, Wellek àti Warren gbàgbọ́ pé kì í ṣe ìṣàwòjíji àwùjọ nìkan ni lítíréṣọ̀ ń ṣe bí kò ṣe pé ó jẹ́ nǹkan tí ó ní í ṣe pẹ̀lú ìkékúrú àti ìsọníṣókí àwùjọ. Adébọ̀wálé (2003:1) sọ pé ìmọ̀-ìbára-ẹni-gbé-pọ̀ láwùjọ tẹpẹlẹ mọ́ àṣà, ìṣe, ìgbàgbọ́ àti ìwòréré ayé àwọn ènìyàn. Bẹ́ẹ̀ ni ó sọ ipa tí àwùjọ lápapọ̀ ń kó lórí ìhùwàsí ẹ̀dá. Ìyẹn fi hàn pé níní ìmọ̀-ìbára-ẹni-gbépọ̀-láwújọ yóò ràn wá lọ́wọ́ láti ní òye nípa ìwà àti ìṣe àwọn ènìyàn inú àwùjọ kan. Ọ̀pẹ́fèyítìmí ṣàlàyé pé orişìíríṣìí ọ̀nà ni onímọ̀ sosiọ́lọ́jì lè gbà tọwọ́ bọṣẹ́ tí

lámèyítọ́ lítíréṣọ̀ ṣe níwọ́n ìgbà tó ṣe pe gbogbo ohun tó jẹ mọ́ lítíréṣọ̀ lápapọ̀ gẹ́gẹ́ bí èso àwùjọ ni iṣẹ́ rẹ̀ dá lé. Nínú àlàyé rẹ̀, ó ní:

> Bó wù ú, ó lè kọjú mọ́ àwùjọ òǹkọ̀wé gẹ́gẹ́ bí ẹ̀dá tàbí òǹkọ̀wé kan. Ó lè wo abala àwùjọ tó hàn nínú iṣẹ́ òǹkọ̀wé. O tún lè wo ìwà tó hàn nínú iṣẹ́ òǹkọ̀wé. Bó wù ú, ó le dágbá lé ìṣẹ̀lẹ̀ àti àtúbọ̀tán tó jẹ́ ẹwù àwùjọ, bó ṣe ń hàn nínú iṣẹ́ òǹkọ̀wé. Bẹ́ẹ̀ gẹ̀gẹ̀ ló lè ṣàtúpalẹ̀ ìlànà ìbáragbépọ̀ àti èrò báyéṣerí (ideology) àti ìdàgbàsókè iṣẹ́ ọnà láwùjọ.

Èyí fi hàn pé àwọn ohun tí ó ń lọ ní àwùjọ ni àwọn ònkọ̀wé ń ṣàfihàn nínú iṣẹ́-ọnà wọn. Ìṣàfihàn bẹ́ẹ̀ lè tako bí nǹkan ṣe rí, kó tàbùkù nǹkan bẹ́ẹ̀, kó sì ṣe ìpènijà fún ìyípadà tàbí kí ó gbóríyìn fún irú nǹkan bẹ́ẹ̀. Ohun tí ó yẹ kó jẹ ẹni tó ń lo tíọ́rì yìí lógún ni láti wá ọ̀nà-àbáyọ sí àwọn ìṣòro tó ń kojú àwùjọ nípasẹ̀ kókó-ọ̀rọ̀ tó ń súyọ nínú afọ̀ lítíréṣọ̀. Níní irùfẹ́ èrò yìí lọ́kàn ló mú kì a gbàgbọ́ pé tíọ́rì ìfojú-ìmọ̀-ìbágbé-pọ̀-láwùjọ-wo-litireṣọ̀ yóò wúlò fún títú àwọn ìwé méjèèjìí palẹ̀.

## Àgbéyẹ̀wò Iṣẹ́ Àtẹ̀yìnwá

Orìṣìíríṣìí ọ̀nà ni àwọn onímọ̀ ti pín ìwé ìtàn-àròsọ si. Ògúnṣínà (1991:17-18) pín ìwé ìtàn-arosọ sí ọ̀nà mẹ́jọ; àwọn ìsọ̀rí náà ni ìwé ìtàn-àròsọ ọmọlẹ́yìn Fágúnwà, ìwé ìtàn-àròsọ mériìírí, ìwé ìtàn-àròsọ àko, ìwé ìtàn-àròsọ ajẹmáwùjọ, ìwé ìtàn-àròsọ ajẹmọ́-ìtàn, ìwé ìtàn-àròsọ ọ̀tẹlẹ̀múyẹ́, ìwé ìtàn-àròsọ amárabùmáṣọ àti ìwé ìtàn-àròsọ ajẹmọ-ìṣèlú. Ògúnṣínà (1992:110) ṣe àtúnpín ìwé ìtàn-àròsọ sí ìsọ̀rí mejì ńláńlá - ìwé ìtàn-àròsọ ọmọlẹ́yìn Fagúnwà àti ìwé ìtàn-àròsọ òde-òní ṣùgbọ́n Adébọ̀wálé (1999:77-78) fi ìsọ̀rí kẹ́ta tí í ṣe ìtàn-àròsọ ajẹmọ́-ọ̀ràn dídá kún un. Ògúnṣínà pìn ìwé ìtàn-àròsọ ọmọlẹ́yìn Fágúnwà sí àwọn tó tẹ̀lé ìlànà Fágúnwa gan-an, àwọn tó wà lágbedeméjì àti àwọn tó jẹ mọ́ ìtàn ìwáṣẹ̀. Ìwé ìtàn-àròsọ ti òde-òní ló pín sí ìwé ìtàn-àròsọ ajẹmọ́-ìtàn gidi, ìwé ìtàn-àròsọ ajẹmáwùjọ àti ìwé ìtàn-àròsọ ọ̀daràn. Ogúnṣínà (1992:165-166) ṣàlàyé pé bí ìwé ìtan-àròsọ òde-òni ti ṣe àfihan ìwà ọ̀làjú tó, wọ́n kún fún ìwà ìbàjẹ́, ìwà àgàbàgebé àti ìwà àgbèrè. Ó ní àfihàn ìwà ọ̀daràn ń gbilẹ̀ sí i. Ọdẹ́jọbí (2004:53) rí ìwà ọ̀daràn bí ìhùwàsi àti ìṣe tí ó lòdì sí òfin, àṣà àti ìṣẹ̀ṣe àwùjọ tí ó lè kó ìyà jẹ irúfẹ́ ẹni tó ṣe bẹ́ẹ̀ yálà nípa rírán an lọ sẹ́wọ̀n, lílé e jáde kúrò nílùú tàbi kí wọ́n pa á. Bí a bá gba oríkì Ọdẹ́jọbí yìí, a jẹ́ pé ìwà ọ̀daràn ni olè jíjà, gbénigbéni, ìdigun-jalè, ìpànìyàn àti àwọn ìwà àìtọ́ mìíràn. Ọ̀nà láti dènà àwọn ìwà ọ̀daràn láwùjọ ló mú kí olórijori mú ọ̀rọ̀ ààbò ní okúnkúndùn èyí kò sì yọ áwọn òǹkọ̀wé alátinúdá sílẹ̀. Níwọ̀n ìgbà tí lítíréṣọ̀ ti ń ṣe àwòjíji àwùjọ, a kò lè fẹ́ ọ̀rọ̀ nípa ìwà ọ̀daràn kù nìnù iṣẹ́ òǹkọ̀wé alátinúdá Yorùbá. Ògúnṣínà (1992) jẹ́rìí sí i pé àfihàn àwùjọ ni àwọn òǹkọ̀wé òde-òní ń ṣe tí wọn sì ń fi òǹkàwé sílẹ̀ láti

máa fa ẹ̀kọ́ yọ fúnrawọn. Ọ̀pọ̀ láméyìítọ́ ló ti ṣiṣẹ́ ìtúpalẹ̀ lórí kókó-ọ̀rọ̀ ajẹmọ́ ìwà ọ̀daràn. Adébọ̀wálé (1995) ṣe àgbéyẹ̀wò iṣẹ́ ọ̀tẹlẹ̀múyẹ́ nínú ìwé ìtàn-àròsọ ajẹmọ́ ọ̀ràn dídá. O fi hàn pé ó kù díẹ̀ káàtó fún àwọn ọlọ́pàá àtipé ẹnikẹ́ni tí ó bá nífẹ̀ẹ́ sí pé kí ìdájọ́ òdodo wáyé lè dìde láti ṣe iṣẹ́ ọ̀tẹlẹ̀múyẹ́. Ìṣọ̀lá (1998:5) gbàgbọ́ pé ìwé ìtàn-àròsọ ọ̀daràn oníjàgídíjàgan tí Ókédìjí kọ bá àwùjọ Yorùbá mu ju ìwé ìtàn-àròsọ ọ̀tẹlẹ̀múyẹ́ tí Akínlàdé kọ nítorí pé ọ̀ràn dídá tí Òkédìjí ṣafihàn wọn jẹ́ àwọn tó wọ́pọ̀ ní àwùjọ Yorùbá. Ògúnṣínà (1992) àti Ìṣọ̀lá (1998) fi hàn pé ìwé ìtàn-àròsọ ọ̀daràn amárabùmáṣọ àti ọ̀tẹlẹ̀múyẹ́ ni Okédìjí àti Akínlàdé kọ. Adéyẹmí (2002) rí Òkédìjí bí ẹni tó ṣe àwòjinlẹ̀ ohun tó ń fa ìwà Ọ́daràn nínú *Atoto Arere*. Abéjide (2016:186-195) fi hàn pé Yorùbá kórìíra ìwà ọ̀daràn, wọn a sì máa fi onírúurú ìyà jẹ ọ̀daràn tí ọwọ́ bá tẹ̀. Àkíyèsí fi hàn pé ọ̀tọ̀ọ̀tọ̀ ni àrokò tí ọ̀kọ̀ọ̀kan òǹkọ̀wé fi ìwé rẹ̀ pa ránṣẹ́ sí àwùjọ.

Nígbà tí a yiiri iṣẹ́ àwọn láméyììtọ̀ wọ̀nyí wò, a rí i pé kò tí ì sí láméyítọ́ tí a mọ̀ tí ó ti yiiri ọ̀ràn dídá nínú ìwé ìtàn-àròsọ méjèèjì wò; èyí ni a lérò pé àlàfo yìí yóò dí. Ìwé ìtàn-àròsọ *Oorun Orí Kẹ̀kẹ́* àti *Oko Aga* tí Olúmúyìwá (2008, 2012) kọ ni a ó yẹ̀wò láti mọ ìhà tí òǹkọ̀wé náa kọ sí ìwà ọ̀daràn ní àwùjọ gẹ́gẹ́ bí ó ṣe hàn nínú àwọn ìwé ìtàn-àròsọ rẹ̀.

## Ogun Ọ̀ràn Dídá Láwùjọ gẹ́gẹ́ bí ó ṣe hàn nínú Ìwé Ìtàn-àròsọ *Oorun Orí Kẹ̀kẹ́* àti *Oko Aga* ti Olúmúyìwá kọ

Òǹkọ̀wé ti fi hàn láti ọ̀rọ̀ àkọ́sọ pé ogun tí ọ̀daràn gbé ti àwùjọ kì í ṣe kèremí. Ó ní:

> Mélòó la ó kà nínú eyín Adépèlé ni ìwà ọ̀daràn tó gbòde kan láwùjọ wa lónìí. Jìbìtì, ìpànìyàn, ìdigunjalè àti gbọ́mọgbọ́mọ ò lóǹkà (*Oorun*: 2008).
>
> Oríṣìíríṣìí ìwà ọ̀daràn bí ìpànìyàn, ìlọ́nilọ́wọ́gbà, ìdìgunjalè, àti jíjínigbé ló kún orílẹ̀-èdè Nàìjá lónìí. Bí àwọn adigunjalè ṣe ń fi ìgbà gbogbo fọ́ àwọn ilé-ìfowópamọ ni àwọn gbọ́mọgbọ́mọ ń jí àwọn ọmọ gbé (*Oko:2012*).

Èròǹgbà òǹkọ̀wé gẹ́gẹ́ bí ó ti sọ ni láti pe àkíyèsí àwùjọ sí onírúurú ogun ọ̀ràn dídá tó ń ja àwùjọ; ṣé bí a bá yọ ipin lójú, a óò fi han ojú kí ojú lè mọ̀ pé òun ń ṣọ̀bùn. Yàtọ̀ sí pé òǹkọ̀wé fúnrarẹ̀ mẹ́nu ba ọṣẹ́ tí àwọn ọ̀daràn ń ṣe ní àwùjọ, ó tún fi ọ̀rọ̀ sẹ́nu ọ̀kan lára ẹ̀dá-ìtàn rẹ̀ olóyè Babatúndé Ọlátúndé, gómìnà ìpìnlẹ̀ Ayénígbà. Àkókò tí olóyè Babatúndé ń dá sọ̀rọ̀ ni ó bẹ̀rẹ̀ sí tú ogun ọ̀ràn dídá tí ó ń ja àwùjọ fó. Ó ní:

> Bẹ́ẹ̀ ibi kan ni àwọn kàràǹbàní tí ó ń dá jìnnìjìnnì bo ìpínlẹ̀ yìí ń gbé.

> Wọ́n sì wà láàrin èrò báyẹn o. Bí wọn ò jọ́mọ gbé, wọn a fi ipá bá obìnrin lò. Bí wọ́n ti ń dánà lọ́sàn-án ni wọ́n ń fọ́lé tìbọn-tìbọn lóru. Àwọn ajẹlójúonílé, Ọ̀fọ́n-ọ̀n. Àwọn ọlọ́pàá sì ń wò wọ́n láìṣe nǹkan sí i (*Oorun* : 23-24).

Ọ̀rọ̀ Babatúndé yìí fi hàn pé àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ tí ó tọ́ka sí kì í ṣe èyí tí ó mú inú àwọn ènìyàn àwùjọ dùn. Ìṣẹ̀lẹ̀ tí ó kó jìnnìjìnnì bo àwùjọ ni gẹ́gẹ́ bí ọ̀rọ̀ rẹ̀. Àfàyọ tí a ṣe nínú àwọn àyọlò òkè yìí ni pé òǹkọ̀wé mọ̀-ọ́n-mọ̀ ṣe àtòjọ àwọn ogun ọ̀ràn dídá nínú àwọn ìwé ìtàn-àròsọ rẹ̀ ni. Ó sì ń fẹ́ kí àwùjọ gbé ìgbésẹ̀ láti mú àyípadà bá àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ adẹ́rùbani àti agbẹ̀mí-ẹni náà. Nínú iṣẹ́ yìí a ó wo oríṣìíríṣìí ogun ọ̀ràn dídá, òkùnfà rẹ̀ àti ọ̀nà àbáyọ gẹ́gẹ́ bí òǹkọ̀wé ti fi wọ́n hàn. A pín ogun ọ̀ràn dídá tí ó ń ja àwùjọ sí ẹlẹ́kajẹ̀ka gẹ́gẹ́ bí a ó ti ṣàlàyé nísàlẹ̀.

## Ogun Olè Jíjà

Òǹkọ̀wé fi hàn pé olè jíjà jẹ́ ọ̀kan pàtàkì lára ogun tí àwọn ọ̀daràn ń gbé ti àwùjọ. Báyọ̀ tí ó jẹ́ àbúrò Bámidélé mọ̀-ọ́n-mọ̀ gbéra láti Èkó láti wá fi ogun olè ja ẹ̀gbọ́n rẹ̀ nípa jíjí ọkọ̀ rẹ̀ gbé nígbà tí onítọ̀hún lọ sí ìṣọ́ òru (*Oko*:1). Onírúurú ète ni àwọn tó ń jí mọ́tò gbé máa ń ta láti lè jẹ́ kí àtijí mọ́tò gbé ó rọrùn fún wọn. Báyọ̀ ṣí iná fún mọ́tò láìní kọ́kọ́rọ́ ọkọ̀ lọ́wọ́. Òǹkọ̀wé fi hàn pé kò dìgbà tí àwọn olè ajímọ́tò bá ní kọ́kọ́rọ́ mọ́tò kí wọ́n tó jí mọ́tò gbé. Èyí fi hàn pé àwọn tó mọ tìfun-tẹ̀dọ̀ mọ́tò ló ń jí mọ́tò. Òǹkọ̀wé sọ pé Báyọ̀:

> ... já wáyà mélòó kan lábẹ́ ibi tí awakọ̀ máa ń jókòó, ó fi wáyà méjì mìíràn ko ara, mọ́tò dáhùn (*Oko*:2)

Kò sí ẹni tí kò mọ̀ nípa iṣẹ́ wáyà tí ó lè ṣe èyí. Ogun ńlá ni Báyọ̀ gbé ti Bámidélé àti ìdílé rẹ̀. Yorùbá bọ̀, wọ́n ní bíkú ilé ò pani, tòde ò lè pani. Bámidélé àti ẹbí rẹ̀ tìṣọ́ òru dé wọn kò ráyè sùn. Ìdààmú bá wọn. Nínú ọgbà Lékan Sàlámì ni wọ́n ti tún jí mọ́tò ọkùnrin kan lára àwọn tí wọ́n lọ wòran bọ́ọ̀lù (*Oorun*:7).

Àwọn olè a tún máa lo ọgbọ́n ẹ̀wẹ́ láti gba owó lọ́wọ́ àwọn ènìyàn. Jọ́ọ̀nù Úmò ni òǹkọ̀wé fi pàrokò irúfẹ́ ìwà yìí. Jọ́ọ̀nù Úmò tí iṣẹ́ ti bọ́ lọ́wọ́ rẹ̀ nítorí tí ó ṣe àṣemáṣe níbi iṣẹ́ aṣọ́bodè fi ọgbọ́n àlùmọ̀kọ́rọ́yí gba owó tí ó tó ẹgbẹ̀rún lọ́nà igba náírà lọ́wọ́ ẹni kọ̀ọ̀kan àwọn ènìyàn tí wọn to àádọ́ta. Jọ́ọ̀nù fún ẹni kọ̀ọ̀kan wọn ní lẹ́tà igbanisíṣẹ́ láti lọ bẹ̀rẹ̀ iṣẹ́ nílé iṣẹ́ aṣọ́bodè ilẹ̀ yìí tó wà ní Àbújá. Àwọn tí Jọ́ọ̀nù fún ní lẹ́tà yìí ti dé ibi iṣẹ́ kí wọ́n tó mọ̀ pé jìbìtì ti lù wọ́n. Onírúurú òǹtẹ̀ àwọn aṣọ́bodè, ìwé ìgbanisíṣẹ́, ibọn àti àwọn ìwé awúrúju mìíràn ni wọ́n bá ní yàrá rẹ̀ (*Oko*: 11). Ogun ńlá ni ó ja àwọn ènìyàn wọ̀nyí. Owó wọgbó, iṣẹ́ kò sí. Èyí lè fa ẹ̀jẹ̀ rírú tí ó sì lè ṣekú pani.

**Ogun Ìdigunjalè**

Ó fẹ́rẹ̀ẹ́ má sí àwùjọ kan tí àwọn adigunjalè kò gbógun tì lóde-òní. Ọ̀pọ̀ ilé-ìfowópamọ́ ni ogun ìdigunjalè lónìí, ogun ìdigunjalè lọ́la ti sọ di abirùn. Àwọn òṣìṣẹ́ ilé-ìfowópamọ́ kò lè ṣe iṣẹ́ wákàtí márùn-ún pẹ̀lú ìfọ̀kànbalẹ̀ lóòjọ́. Ojoojúmọ́ ni wọ́n ń retí lẹ́tà láti ọ̀dọ̀ àwọn adigunjalè, wọn kò lè fẹ̀dọ̀ lérí òróòro ṣiṣẹ́. Bí wọ́n bá gbúròó ogun ìdígunjalè ní báǹkì mẹ́wàá sí tiwọn, wọn yóò sáré gbé lẹ̀kùn wọn tì. Bí adigunjalè bá ń fọ́ báǹkì, ìró ìbọn, ìpayà, ìkólọ́kànsókè tí ó ń dé bá àwọn ènìyàn máa ń dàbí ìgbà tí ènìyàn wà lójú ogun gan-an ni. Bí àwọn adigunjalè ṣe ń yìnbọn sí òfurufú ni wọn yóò máa fi bọ́ǹbù fọ́ ẹnu ọ̀nà àbáwọlé ilé-ìfowópamọ́ kọ̀ọ̀kan bírú èyí tí ó wáyé ní ìlú Ìpalẹ̀fà níbi tí àwọn adigunjalè ti fọ́ báǹkì mẹ́ta ọ̀tọ̀ọ̀tọ̀ tí wọ́n fẹ̀gbẹ́ ti ara wọn (*Oko:73*). Òǹkọ̀wé fi ìṣẹ̀lẹ̀ tí ó wáyé ní Ìpalẹ̀fà ní àkókò tí àwọn adigunjalè ń fọ́ ilé-ìfowópamọ́ mẹ́ta parokò ìhùwàsí àwọn adigunjalè àti èrò àwùjọ ní àkókò tí ìdigunjalè ń lọ lọ́wọ́. Ó ní:

> Déédé ọjọ́ kanrí ni bọ́ǹbù dédé dún 'gbòà!' Àwọn ènìyàn ń sá lu ara wọn. Ṣàdédé ni ìbọn bẹ̀rẹ̀ sí dún lákọlákọ. Àwọn jàgùdà ti gbé àwọn ọkọ̀ bọ́ọ̀sì dí ọ̀nà ní apá ọ̀tún àti apá òsì òpópónà Onígángan. Wọ́n fi èèyàn méjì méjì sídìí ọkọ̀ kọ̀ọ̀kan. Àwọn wọ̀nyí ń rọ̀jò ìbọn sí òfurufú (Oko:73)

Gẹ́gẹ́ bí ohun tí òǹkọ̀wé sọ, ìdí ìbọn ni àwọn adigunjalè wọ̀nyí fi fọ́ ilẹ̀kùn ọ̀nà àbáwọlé ilé-ìfòwópamọ́ kọ̀ọ̀kan tí wọ́n wọ̀. Ohun tí òǹkọ̀wé tún pe àkíyèsí àwùjọ sí ni àìsí ìbọn lọ́wọ́ àwọn ẹ̀ṣọ́ ààbo inú ọgbà ilé-ìfowópamọ́. Ó ṣàlàyé pé:

> Ìgbà tí bọ́ǹbù ti dún lákọlákọ ni gbogbo àwọn ẹ̀ṣọ́ ààbò inú ọgbà ilé-ìfowópamọ́ wọ̀nyí ti wá ibi gbà. Wọ́n kàn fi wọ́n dí gẹrẹwu síbẹ̀ ni, kò sí ìbọn lọ́wọ́ wọn (Oko:73).

Kí ni àjọ ọlọ́pàá tó fi wọ́n síbẹ̀ ń fẹ́ kí wọ́n fi jagun ìdigunjalè tí ó ń ja ilé-ìfowópamọ́ náà, ìdí niyẹn tí àwọn ẹ̀ṣọ́ náà fi sá àsálà fún ẹ̀mí wọn. Máníjà ilé ìfowópamọ́ kọ̀ọ̀kan ló wá àpò ṣaka tí wọ́n fi di owó, àwọn pẹ̀lú aṣírò-owó wọn ló bá àwọn adigunjalè gbé owó dé ìdí ọkọ̀ wọn (*Oko*:73). Bí Yorùbá bá ń jagun, oríṣìíríṣìí ète ogun ni wọ́n ń lò láti rí i pé wọn rí ọ̀tá mú. Bákan náà ni ètekéte kún ọwọ́ àwọn adigunjalè gẹ́gẹ́ bí a ti rí i nínú ìwé ìtàn-àròsọ *Oko Aga* níbi tí olórí adigunjalè ti yí ohùn rẹ̀ padà sí ti Oyètòrò, oníbàárà ilé-ìfowópamọ́ Oníràwọ̀ pàtàkì kan. Ète ṣíṣe èyí ni láti jẹ́ kí ọ̀gbẹ́ni Òwòrú tí ó jẹ́ mánújà lè ṣètò láti ṣí ilẹ̀kùn Ilé-ìfowópamọ́ tí wọ́n ti tì nítorí àwọn adigunjalè tí àwọn òṣìṣẹ́ gbọ́ pé wọ́n fọ́ báǹkì ní ìlú Ìpalẹ̀fà fún un. Olórí adigunjalè yìí fúnra rẹ̀ ló sọ irúfẹ́ ọgbọ́n tí ó fi mú ọ̀gbẹ́ni Òwòrú tí ó jẹ́ mánújà lẹ́yìn tí ó jà á lólè tán lọ́nà àtifi mánújà náà ṣe yẹ̀yẹ̀. Ó ní:

> N ò nílò láti sọ fún ọ pé èmi kì í ṣe olóyè Oyètòrò. Iṣẹ́ ọpọlọ ló rí yẹn. Gbogbo àwọn oníbàárà yín tó ṣe pàtàkì ni a mọ̀. Ṣé o rí pé orí awà náà pé bi tìrẹ (*Oko*:78).

Ọkọ̀ ayọ́kẹ́lẹ́ báǹkì ni wọ́n fi di owó lọ lẹ́yìn tí adigunjalè ti fi ìbọn fọ́ aṣírò-owó tí olórí adigunjalè gbàgbọ́ pé ó fi àkókò òun ṣòfò lẹ́sẹ̀. Ọ̀pọ̀ ẹ̀mí àwọn oníbàárà ni àwọn adigunjalè máa ń gbà ní àkókò tí wọ́n bá fọ́ báǹkì yìí. Bí irúfẹ́ èyí tí ó wáyé nígbà tí wọ́n fọ́ ̀báǹkì Elérin níbi tí wọ́n ti pa olùkọ́ kan àti obìnrin tí ó gba ìpè ní àkókò tí wọ́n ń ṣọṣẹ́ lọ́wọ́. Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé ẹ̀san àìkọ́ni dójú àmì ni olè tí ó pa olùkọ́ sọ pé ó ké lórí olùkọ́, ohun tí a mọ̀ ni pé àkókò tí wọ́n ń fọ́ báǹkì ni olùkọ́ náà ríkú he (*Oko*:88).

Bí àwọn adigunjalè ṣe ń fọ́ ilé ìfowópamọ́ lọ́sàn-án ni wọ́n ń fọ́ ilé lóru. Ilé méjọ ni wọ́n fọ́ lọ́jọ́ kan ṣoṣo ní àdúgbò Òkè-Ọlà. Òǹkọ̀wé jẹ́ kí a mọ̀ pé ìbọn A.J.47 (gẹ́gẹ́ bí ìpèdè òǹkọ́wé, *Ooru*n:41) ni ọ̀kọ̀ọ̀kan àwọn olè mẹ́rin tó wá sí àdúgbò náà ní lọ́wọ́ bẹ́ẹ̀ àwọn ọlọ́pàá tó ń ṣọ́ ilé ìfowópamọ́ kò níí ìbọn ṣakabùlà lásán. Àrokò tí òǹkọ̀wé ń fi èyí pa ránṣẹ́ sí àwùjọ ni pé àìní ohun èlò àwọn agbófinró tàbùkù iṣẹ́ wọ́n kò sì jẹ́ kí wọ́n lè dojú ogun kọ àwọn adigunjalè bí ó ti yẹ. Òǹkọ̀wé fi hàn pé akọ òkúta ńlá ràbàtà kan ni àwọn ọlọ́ṣà náà fi já ilẹ̀kùn àbáwọlé ilé Sájẹ́ǹtì Ẹnilaṣọ láti ìta (*Ooru*n: 41). Nílé Ọlábísí, bí ó ṣe fi ìgboyà dá àwọn adigunjalè lóhùn pé ọkọ òun kò gbówó wálé tó, àwọn adigunjalè pàpà fi irin fọ́ ilẹ̀kùn ẹnu ọ̀nà wọlé, wọ́n sì rí i dájú pé Ọlábísí fi ojú gba ìbọn kí wọ́n tó fi ilé rẹ̀ sílẹ̀ (*Oorun* 30).

Ọ̀pọ̀ ni àwọn adigunjalè máa ń ká mọ́ òtẹ́ẹ̀lì ti wọn yóò gba ohun gbogbo tí wọ́n ní. Òǹkọ̀wé fi Ọlábọ̀dé pàrokò irúfẹ́ ìṣẹ̀lẹ̀ yìí nínú *Oko Aga* níbi tí àwọn adigunjalè ti ká Ọlábọ̀dé tí ó ṣẹ̀ṣẹ̀ ti ìlú òyìnbó dé mọ́ òtẹ́ẹ̀lì. Gbogbo owó tí ó ní ni wọ́n gbà. Tìbọn-tìbọn ni ọ̀kan nínú àwọn adigunjalè fi sọ fún Ọlábọ̀dé pé "Owó wa tí o kó ti ìlú òyìnbó dé ni a wá gbà" (*Oko*:59) láìmọ àsìkò tí onítọ̀hún lọ sí ìlú òyìnbó.

Ogun yìí kò yọ ilé Ọlọ́run sílẹ̀; àwọn adigunjalè fi ìbọn gba owó àti ẹ̀rọ ìbánisọ̀rọ̀ nínú ìṣọ́ òru ìjọ aládùúrà tí ó wà ní Òkè-Ìlá (*Oko*: 4). Inú ìsìn Ìkórè ti ìjọ Oníhìnrere Mẹ́talọ́kan tí ó wà ní àdúgbò Ìṣèlú ní ìlú Òyè ni àwọn adigunjalè ti fi ìbọn gba gbogbo owó tí ìjọ rí nínú àjọ̀dún ìkórè ọdún náà (*Oorun* 39).

Òǹkọ̀wé tún fi hàn pè ọ̀pọ̀ ìgbà ni àìkíyèsára máa ń fa ènìyàn lé ogun ọ̀ràn dídá lọ́wọ́. Àwọn tí wọ́n wọ ọkọ̀ sọ́ọ̀lẹ̀ tí kò ní nọ́ńbà ni òǹkọ̀wé fi pàrokò irúfẹ́ ìwà yìí. Òǹkọ̀wé fìdí èrò yìí múlẹ̀ nígbà tí ó mú kí awakọ̀ àti àwọn méjì mìíràn tó pèrò sọ́kọ̀ tí ó ń lọ sí Kójúmárìíbi fi ìbọn gba gbogbo owó, aago-ọwọ́, ẹ̀gbà ọrùn àti yẹtí èrò ọkọ̀ nígbà tí wọ́n dé ààrín ọ̀nà. Nígbà tí Kọ́míṣọ́nnà Ìdòwú gbọ́ pé ọkọ̀ tí kò ní nọ́ńbà ni wọ́n wọ̀, ó bi wọ́n bí wọ́n ṣe fẹ́ kí ọlọ́pàá mú ọkọ̀

tí ò ní nọ́ńbà. Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé àwọn adigunjalè ló tún lo ọgbọ́n ẹ̀wẹ́ láti kó àwọn ènìyàn lọ sí àárín ọ̀nà lọ fìbọn gba owó lọ́wọ́ wọn, ogun àfọwọ́fà ni a lè pe èyí. Òǹkọ̀wé ń dọ́gbọ́n pe àkíyèsí àwùjọ sí ewu tó wà nínú wíwọ ọkọ̀ sọ́ọ̀lẹ̀. Ó fi ọ̀rọ̀ sí Kọ́míṣọ́nnà Ìdòwú lẹ́nu nígbà tí onítọ̀hún ń gba àwọn tọ́rọ̀ kàn nímọ̀ràn, ó sọ pé:

> Ṣé ẹ̀yin náà wá rí i báyìí pé ìkánjú àti sùúrù, ọgba ni. Ṣé sùúrù gan-an ò ju ìkánjú lọ báyìí? Ó yẹ kí ẹ̀yin tí ẹ bá fẹ́ wọkọ̀ lè máa ní sùúrù kí mọ́tò tí ó bá ń lóòdù nínú gáréèjì fi kún. Ó léwu lọ́pọ̀lọ́pọ̀ láti wọ mọ́tò lẹ́bàá ọ̀nà. Ọ̀kan lára ewu ibẹ̀ lẹ rí yìí (*Oorun*:33).

## Ogun Ìjínigbé

Òǹkọ̀wé pe àkíyèsí èrò àwùjọ sí ogun ìjínigbé tó ń ja àwùjọ. Ogun ìjínigbé kò lóǹkà ní àwùjọ wa lónìí. Bí wọ́n ṣe ń jí ọmọdé gbé ni wọn ń jí àgbà gbé. Ní ojú ìwé kẹ́sàn-án ni òǹkọ̀wé ti ṣe àfihàn Ikéńnà àti àwọn méjì mìíràn tí wọ́n jí ọmọ ọdún méjì gbé. Ó gbé ọmọ náà lọ sọ́dọ̀ Alíìsì láìjẹ́ kí onítọ̀hún mọ̀ pé ṣe ni ó jí ọmọ náà gbé. Wọn béèrè fún milíọ̀nù márùn-ún kí wọ́n tó lè dá ọmọ náà sílẹ̀ ṣùgbọ́n ọwọ́ tẹ̀ wọ́n níkẹyìn (*Oko*: 9). Dáúdà Babátúndé awakọ̀ jí Kíkẹ́lọmọ, akẹ́kọ̀ọ́ tí ó ń padà sílé láti ilé-ẹ̀kọ́ gbé. Ọpẹ́lọpẹ́ ìwé tí ó kó mọ́yà ni kò jẹ́ kí ọfọ̀ tí ó pè sí alábaun ran Kíkẹ́lọmọ nígbà tí Babatúndé fi alábaun náà gbá Kíkẹ́ láyà (*Oko*:10). Ogun ìjínigbé tún ja àwùjọ nígbà tí àwọn ajínigbé jí ọkọ̀ àwọn ọmọ ilé-ẹ̀kọ́ alákọ̀ọ́bẹ̀rẹ̀ Tèmilayọ̀ tí ọmọ mẹ́ẹ̀dógún wà nínú rẹ̀ gbé. Ara onílé àti alejò kan gógó. Ẹni tí ọ̀rọ̀ kàn àti ẹni tí ọ̀rọ̀ kò kàn ló pariwo. Tọbatọba ni àwọn ajínigbé wọ̀nyí ń jí. Oníròwò ti Ìròwò ni òǹkọ̀wé fi pàrokò ọba tí wọ́n jí gbé. Àwọn ajínigbé yìí béèrè fún igba mílíọ̀nù náìrà. Nígbà tí kò sí ẹni tó rí ti-wọn rò tí ó jẹ́ pé èpè ni àwọn ará ìlú ń ṣẹ́ fún àwọn tó lọ́wọ́ nínú jíjí ọba náà gbé, ọjọ́ kẹ́ta ni wọ́n bá òkú Oníròwò lẹ́gbẹ̀ẹ́ ọ̀nà tí ó wọ ìlú Ìròwò; wọ́n ti yọ ojú àti nǹkan ọmọkùnrin rẹ̀ lọ (*Oko*:81). Ìrísí òkú Oníròwò yìí fi hàn pé owó ni o jẹ àwọn ajínigbé náà lógún nígbà tí wọn kò sì rí owó wọ́n kúkú fi ẹ̀yà ara rẹ̀ ṣe oògun owó. Ó sì lè ṣe é ṣe kí ó jẹ́ pé ṣe ni àwọn ajínigbé ta ẹ̀yà ara yìí ní iyé owó tí wọ́n ń retí kí ìlú san ṣùgbọ́n tí wọn kò san. Ọjọ́ tí wọ́n rí òkú Oníròwò ti Ìròwò ni àwọn ajínigbé tún jí bàbá àti àkọ́bí gómìnà Ṣànúsí gbé. Àwọn ajínigbé béèrè fún ẹ̀ẹ́dẹ́gbẹ̀ta mílíọ̀nù náírà lórí ẹni kọ̀ọ̀kan wọn. Wọ́n tilẹ̀ tún ṣe ìkìlọ̀ fún gómìnà Ṣànúsí pé:

> Agídí ò ràn án. Òtúbáńtẹ́ sì ni akitiyan àwọn ọlọ́pàá lórí ọ̀rọ̀ náà. Ṣe kánkán, ìjáfara léwu o. Má jẹ́ kí ọ̀rọ̀ wọn dàbí ti Oníròwò o (*Oko* :82).

A tún rí bí àwọn ajínigbé ṣe jí ìyá Ọlátúndé alákòóso fún ètò ìròyìn ìpínlẹ̀

Olómi-méjì gbé ní ìlú Ìjọ̀kà, wọ́n béèrè fún ọgbọ̀n mílíọ́nù náírà. Ìdàámú ńlá ni ogun wọ̀nyí kó àwọn ènìyàn àwùjọ sí. Ọ̀nà àtidi olówó òjijì ló mú kí àwọn ènìyàn sọ ara wọn di ajínigbé àti ajíniṣètùtù-ọlà. Irúfẹ́ ìwà yìí ta ko àlááfíà àwùjọ. Ọkàn àwọn ará ìlú kò lè balẹ̀ ní àwùjọkáwùjọ tí irúfẹ́ ogun yìí bá ti ń jà. Òǹkọ̀wé fi hàn pé àwọn ajínigbé máa ń lo oríṣiríṣi ète ní ọ̀pọ̀ ìgbà kí èrò àwùjọ má ba à mọ irúfẹ́ iṣẹ́ tí wọ́n ń ṣe. Òǹkọ̀wé ṣe àfihàn obìnrin kan tó sọ ọmọ méjì di ewúrẹ́ tó sì kó wọn sínú àpò ṣaka kan. Ọpẹ́lọpẹ́ Sájẹ́ǹtì Ọlátúnjí tí ó gbọ́ èdè ẹranko ní ó tú obìnrin náà láàṣírí. Ohun tí òǹkọ̀wé ń dọ́gbọ́n sọ ni pe àwọn ọlọ́pàá nílò àfikún ẹ̀kọ́ lati le ṣe aṣeyọrí nídìí iṣẹ́ wọn pàápàá ní àkókò tí ìwà ọ̀daràn gbòde kan ní àwùjọ. Bí àpẹẹrẹ, àfikún ìmọ̀ tó wúlò fún àṣeyọrí ni fún ọlọpàá tó bá gbọ èdè ẹranko gẹ́gẹ̀ bí ó ti wúlò fún Sajẹnti Ọlatúnji (bí ẹnu kò tilẹ̀ kò lórí bóyá ẹranko ní èdè tàbí kò ní). Pepperberg (2017) fi hàn pé ẹranko a máa bá ara wọn sọ̀rọ̀ láti fi ìmọ̀sílára bí ebi tàbí ẹ̀rù hàn. Ìmọ̀ sáyẹ́ǹsì fi ye ni pe a lè bá ẹranko sọ̀rọ̀ (https://blogs.scientificamerican.com.). Fágúnwà (2005:100) mẹ́nu ba gbígbọ́ èdè ẹranko nigbá tí ó mú kí ọ̀kan nínú ẹ̀dá-ìtàn rẹ̀ gbọ́ èdè tí àgbébọ̀ adìyẹ ń bá àwọn ọmọ rẹ̀ sọ èyí tí ó sọ ẹ̀dá-ìtàn náà di olówo (*Igbó Olódùmarè*: 100). Òǹkọ̀wé tún fi ìṣẹ̀lẹ̀ yìí pe àkíyèsí àwùjọ sí ewu tó wà nínú kí ènìyàn máa he owó nílẹ̀. Owó tí obìnrin náà sọ sílẹ̀ ni àwọn ọmọ náà mú tí wọ́n sì di ewúrẹ́.

## Ogun Ìfiniṣètùtù

Òǹkọ̀wé fìdí rẹ̀ múlẹ̀ pé àwọn kan a máa fi ènìyàn ṣètùtù láti wá agbára. Ní ọ̀pọ̀ ìgbà àwọn tó lórúkọ ní ìlú ni a máa ń bá nìdìí irúfẹ́ ọ̀ràn dídá bẹ́ẹ̀. Àwọn ohun tí wọ́n ń lò kí wọ́n tó rí irúfẹ́ agbára bẹ́ẹ̀ ta ko àlááfíà àwùjọ. Òǹkọ̀wé fi Gómìnà Adégbóyèga pàrokò irúfẹ́ ìhùwàsí yìí. Nínú ìwé ìtàn-àrosọ *Oko-Aga*, a rí Gomìnà Adégbóyèga tí awo ọparun ń fi ẹ̀jẹ̀ ọmọ òòjọ sí ọjọ́ mẹ́sàn-án wẹ orí fún lóṣooṣù láti wá agbára kún agbára àti láti jẹ́ kí abẹ gé ohunkóhun tí ó bá sọ; ohunkóhun tí ó bá sì ṣe aṣegbé ni. Irúfẹ́ ìfi ọmọ ṣètùtù bírú èyí ti sọ ọmọ di títà ní àwọn ilé ìwòsàn káàkiri. Òǹkọ̀wé fìdí èrò yìí múlẹ̀ nígbá tí ó sọ pé:

Àtijọ́ ni kò ti sọ́mọ látẹ. Àtirí ọmọ rà lọ́jà lónìí kò ṣòro pàápàá ní ìpínlẹ̀ Èbìtà. Ṣàṣà ni ilé ìwòsàn adáni tí kì í tọmọ (*Oko*:50).

Òǹkọ̀wé ṣàlàyé àwọn ọ̀nà tí wọ́n ń gbà rí àwọn ọmọ náà nígbà tí ó sọ pé:

> Ilé-ìwòsàn kan tilẹ̀ wà ní ìlú Kòkódìyà tí wọ́n ń pè ní ilé àánú. Ó kéreé tán lóṣù ọmọbìnrin bí mẹ́ẹ̀dógún tí ó gboyún ń bẹ níbẹ̀ tí wọ́n ń gba ìtọ́jú ọ̀fẹ́. Ẹ̀kọ ń wọlé, ewé ń jáde ni àwọn ọmọbìnrin wọ̀nyí ń fi oyún ṣe (*Oko*:50).

Òǹkọ̀wé ṣàlàyé síwájú sí i pé bí àwọn ọ̀dọ́bìnrin bá bímọ tán, Aṣọ́ḿbà tó ni ilé-

iṣẹ́ náà yóò fún wọn ní ẹgbẹ̀rún lọ́nà ọgbọ̀n náírà bí wọ́n bá ń lọ. Òǹkọ̀wé fìdí rẹ̀ múlẹ̀ pé àwọn ilé àánú kan a tilẹ̀ máa san tó ẹgbẹ̀rún lọ́nà ọ̀ọ́dúnrún náírà lórí ọmọ kan. Àwọn ọ̀dọ́bìnrin tipasẹ̀ irúfẹ́ ìwà bẹ́ẹ̀ sọ ibẹ̀ di ilé-iṣẹ́ ọmọ bíbí. Àti àwọn gboyúngboyún àti àwọn tó ń ra ọmọ tà fún àwọn tó ń fọmọ ṣètùtù, gbogbo wọn ló gbógun ti àwùjọ. Ogun mìíràn tí ó ti inú irúfẹ́ ọ̀ràn dídá yìí jáde ni ìmùlẹ̀ ṣíṣe. Ọ̀pọ̀ ẹgbẹ́ ìmùlẹ̀ ló ń gbógun ti àwùjọ. Ìmùlẹ̀ tí àwọn oníṣẹ́ ibi wọ̀nyí wọ̀ ni kì í jẹ́ kí àṣírí wọn tètè tú; ìyẹn bí yóò bá tilẹ̀ tú rárá. Kò sí ẹni tí ó fẹ́ ta ọmọ, tí ó fẹ́ fọmọ ṣètùtù tàbí tó fẹ́ kí wọ́n fi ẹ̀jẹ̀ ọmọ wẹ̀ òun lórí tí kò níí mulẹ̀. Ọ̀pọ̀ ẹgbẹ́ ìmùlẹ̀ wọ̀nyí ṣetán láti fi ipá mú ẹnikẹ́ni tó bá mọ àṣírí wọn láti dara pọ̀ mọ́ wọn. Òǹkọ̀wé fi Kọ́lá pàrokò irúfẹ́ ìsọdọmọẹgbẹ́ bẹ́ẹ̀. Ní kété tí olórí awo ti mọ̀ pé Kọ́lá tí ó jẹ́ olórí àwọn ẹ̀ṣọ́ ààbò fún gómìnà Adégbóyèga ti rí wọn ni ó sọ ọ́ di ọ̀kan lára wọn nípa mímú kí ó mu ẹ̀jẹ̀. Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé Kọ́lá mulẹ̀ pẹ̀lú àwọn awo ọparun tí gómìnà sì ti sọ fún ún pé ọ̀rọ̀ náà ti di ìmùlẹ̀, síbẹ̀, Adégbóyèga kò ní ìgbẹ́kẹ̀lé nínú Kọ́lá, ó gbé àpò owó tí àdó olóró wà nínú rẹ̀ fún un. Ibi tí Kọ́lá ti ń ṣí àpótí owó ni àdó olóró tí ó gbẹ̀mí Kọ́lá ti dún. Ogun ibiṣẹ́ ló ja Kọ́lá níhìn-ín bí ó ti ń ja àwọn ènìyàn àwùjọ. Ohun tí òǹkọ̀wé dọ́gbọ́n ń sọ ni pé ó níbi tí ènìyàn lè ṣe òfíntótó iṣẹ́ mọ. Ènìyàn sì gbọ́dọ̀ máa kíyèsára níbi iṣẹ́kíṣẹ́ tí ó bá ń ṣe kí ó má ba à kàndin nínú iyọ̀; ẹ̀mí iṣẹ́ gùn ju ẹ̀mí èèyàn lọ.

## Ogun Ìpànìyàn

Ọ̀kan lára ogun tí òǹkọ̀wé tún tọ́ka sí ni Ogun ìpànìyàn. Ilé Ọláòtán oníbúrẹ́dì ni àwọn agbanipa ti yìn ín níbọn ní ààjìn (*Oorun*: 28). Olè ló pa ọlọ́pàábìnrin Kọ́bùrù Ìyábọ̀ lẹ̀yìn tí wọ́n ti fipá bá a lò pọ̀. Ogun ìfipábánilòpọ̀ ló ja ìyábọ̀ kí ogun ìpànìyàn tó tún jà á. Àbúrò rẹ Doyin ni wọ́n tún fẹ́ fi ipá bá lò pọ̀ tí ìyábọ̀ yarí ni wọ́n bá gbé ìbọn fún un. Inú ṣọ́ọ̀ṣì ni wọ́n ti yìnbọn pa olóṣèlú kan tó fẹ́ díje sí ipò gómìnà (*Oko*:93). Sọ́ńdè Ùmọ́rìà bẹ́ ìyàwó rẹ̀ lórí, ó ní ó ṣe àgbèrè, ó sì tipasẹ̀ bẹ́ẹ̀ fi ogun ja ìdílé rẹ̀. Ó sọ àwọn ọmọ di aláìníyàá. Níwọn ìgbà tí ó jẹ́ pé ẹni tó bá pànìyàn pípa náà ni a ó pa á, ogun yìí ti sọ àwọn ọmọ di aláìlóbìí. Ara àtubọ̀tán ogun ni èyí. Ojú ìwé kẹfà ìwé *Oko Aga* ni a ti rí bí àwọn agbingbó ṣe dojú ìbọn kọ àwọn òṣìṣẹ́ àjọ tí ń gbógun ti oògùn olóró NDLEA tí wọ́n sì rán méjì nínú wọn lọ́run ọ̀sán gan-gan.

Òǹkọ̀wé pé àkíyèsí àwùjọ sí i pé nígbà mìíràn, ogun àìmọ̀dí a máa fa ènìyàn lé ogun ìpànìyàn lọ́wọ́. Ọ̀pọ̀ ìdájọ́ tí àwọn ènìyàn ń ṣe fún àwọn ọ̀daràn ni kò dúró lórí òótọ́, ṣé orí yéye nìmògún, tàìṣẹ̀ ló pọ̀. Ìrúfẹ́ ìdájọ́ yìí a máa wáyé nítorí àìfarabalẹ̀ ṣe ìwádìí kí wọ́n tó gbé ìgbésẹ̀. Irúfẹ́ ìṣẹ̀lẹ̀ yìí ni òǹkọ̀wé fi hàn níbi tí àwọn ènìyàn ti dáwọ́jọ lu Músá tí kò mọwọ́-mẹsẹ̀ nínú ogun gbájúẹ̀ tí Báyọ̀ fi ja Aúdù pa (*Oko*:16). Àìfarabalẹ̀ wádìí ẹni tí ASP Ukwa jẹ́ ni ikọ̀ àwọn ọlọ́pàá tó

ń ṣọ́ ẹnu odi ìlú Ìjọkà fi rọ̀jọ̀ ìbọn lé e lórí tí wọ́n sì rán an sọ́run ọ̀sán gangan (Oko:87). Ṣe ni òǹkọ̀wé dọ́gbọ́n ń sọ fún àwùjọ pé àìfarabalẹ̀ ṣe ìwádìí kí ìdájọ́ tó tẹ̀lé e kò yọ ọlọ́pàá gan-an sílẹ̀.

## Okùnfà Ogun Ọ̀ràn dídá tó ń ja àwùjọ gẹ́gẹ́ bí ó ṣe hàn nínú Ìwé Ìtàn-àròsọ *Oorun Orí Kẹ̀kẹ́* àti *Oko Aga*

Òǹkọ̀wé kò ṣàì fi ọ̀rọ̀ sẹ́nu àwọn ẹ̀dá-ìtàn rẹ̀ tí wọ́n jẹ́ ọ̀daràn láti fi tó àwùjọ létí ohun tí wọ́n rí lọ́bẹ̀ tí wọ́n fi wàro ọwọ́ léte àtipe àkíyèsí àwùjọ sí àwọn okùnfà ogun ọ̀ràn dídá tó ń ja àwùjọ. Oríṣìíríṣìí nǹkan ló ṣe okùnfà ogun ọ̀ràn dídá wọ́nyí gẹ́gẹ́ bí a ti rí i nínú àwọn ìwé ìtàn-àròsọ tí a yẹ̀ wò.

## Àìní Ìtọ́jú

Òǹkọ̀wé fi hàn pé bí ọmọ kò bá ní ìtọ́jú tí ó péye, ó lè dí ẹni tó ń gbógun ti àwùjọ. Owónikókó tó sọra rẹ̀ di Màràdónà ni òǹkọ̀wé fi pàrokò irúfẹ́ ìwà yìí. Àbúrò bàbá Owónikókó tí ó jogún ohun ìní àwọn òbí Owónikókó kò lè tọ́jú Owónikókó bí àwọn òbí rẹ̀ ti ń ṣe nígbà tí wọ́n wà láyé. Ìgbà tí ọwọ́ ìyà tẹ Owónikókó ló jáde nílé tó di ẹni tí ó ń sun abẹ́ búkà. Ibẹ̀ ni òun àti Ṣọ̀ṣọ ti pàdé tí wọ́n jọ ń ṣe àfọ́wọ́rá ní ìdíkọ̀ èrò ní Aráròmí. Ọ̀pọ̀ ẹ̀mí ló tọ́wọ́ Owónikókó bọ́. Bí àpẹẹrẹ, òun ni Kọ́lá Àlàó rán láti lọ pa Ọláòtán oníbúrẹ́dì.

## Ìwà Àìgbọ́ran

Ìwà àìgbọ́ran tún jẹ́ ohun pàtàkì tí òǹkọ̀wé tọ́ka sí gẹ́gẹ́ bí ọ̀kan lára ohun tó lè fa ọ̀ràn dídá. Ó fi Jímọ̀ Ale pàrokò irúfẹ́ ìwà bẹ́ẹ̀. Láti kékeré ni Jímọ̀ Ale tí ó jẹ́ ọmọ ọdún méjìdínlógún ti bẹ̀rẹ̀ olè jíjà (*Oorun* 94). A maa yọ ẹran jẹ nínú ìṣasùn ìyá rẹ̀. Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé obí rẹ̀ máa ń nà án síbẹ̀ kò gbọ́ gẹ́gẹ́ bí òun fúnrarẹ̀ ti jẹ́wọ́ níkẹyìn. Inú sinimá ló ti kọ́ ìbọn yínyìn. Àwọn òbí níláti sa gbogbo ipá wọn láti gba ìwàkíwà kúrò lọ́wọ́ àwọn ọmọ nígbà tí wọ́n bá ṣì wà ní kékeré. Púpọ̀ ohun tí wọ́n ń ṣe ní kékeré ló ń sọ ohun tí wọn yóò jẹ́ lẹ́yìn ọ̀la.

## Ìyapa láàrin tọkọ-taya

Bí ọkọ àti aya kò bá pawọ́ pọ̀ tọ́jú ọmọ, irúfẹ́ ọmọ bẹ́ẹ̀ lè yayakúyà. Bàbá àti ìyá Dáfídì Òdìdí ti pínyà láti ìgbà tí Dáfídì ti jẹ́ ọmọ ọdún mẹ́rin, kò sì sí ìtọ́jú fún ún tìtí tí ó fi lọ dara pọ̀ pẹ̀lú àwọn olè tí ó sì di apànìyàn.

## Àìní Ìtẹ́lọ́rùn

Fọga ni Kúnlé ní tirẹ̀ tí ó fi pàdé Màràdónà tí ó fi ń bá a ṣiṣẹ́. A lè sọ pé àìní ìtẹ́lọ́rùn ló fa ẹgbẹ́kẹ́gbẹ́ tí Kúnlé wọ̀. Ó fẹ́ láti di olówó lójijì. Àgbàlagbà ni Jọ̀ọ̀nù Ajíṣọlá, owó tí yóò fi ṣòkú àna ló mú kí ó lọ dara pọ̀ mọ́ ẹgbẹ́ olè. Àìfẹ́ ṣe bí agbára rẹ̀ ti mọ ló mú kí ó lọ bá wọn jí owó nílé Ọlọ́run lọ fi ṣòkú àna.

Òǹkọ̀wé dọ́gbọ́n ń pe àkíyèsí àwùjọ sí ìhà tí àwùjọ kọ sí òkú ṣíṣe. Ó fẹ́ kí àwùjọ yí èrò wọn lórí òkú ṣíṣe padà. Kò yẹ kó dìgbà tí ènìyàn bá wọ gbèsè tàbí tí ó lọ jalè kí ó tó ṣe òkú yàlà ti òbí ni tàbí ti àna ẹni.

## Wíwọ Ẹgbẹ́ Òkùnkùn

Ẹgbẹ́ òkùnkùn wíwọ̀ náà a máa ṣe okùnfà ọ̀ràn dídá tí ó ń fogun ja àwùjọ. Múkà Ọláníyan, ọmọ ọdún mẹ́rìnlélógún jẹ́ ìsáǹsá láti ilé-ẹ̀kọ́ girama. Ó dara pọ̀ mọ́ ẹgbẹ́ òkùnkùn ní ilé-ẹ̀kọ́ gíga Yunifásítì. Nígbà tí ó ń bá akọ̀ròyìn sọ̀rọ̀, ó ní:

> Mo wọ Yunifásítì. Mo débẹ̀ tán mo dara pọ̀ mọ́ ẹgbẹ́ òkùnkùn, ẹgbẹ́ burúkú, ẹgbẹ́ ẹyẹ. A ń jayé bí ẹni jẹ iṣu. A ń pa ènìyàn lẹ́kún. A ń gba ọ̀rẹ́bìnrin àwọn ẹgbẹ́ wa; wọn ò sì gbọ́dọ̀ sọ̀rọ̀. A ń mu ẹ̀jẹ̀ ènìyàn. A sì máa ń fi agbárí ènìyàn mu omi. Háà! ẹgbẹ́ burúkú ni ẹgbẹ́ òkùnkùn. Kò dáa fún ọmọlúwàbí (*Oorun:* 97).

Láti yunifásítì ló ti dara pọ̀ pẹ̀lú Màràdónà adigunjalè.

### Ìhùwàsí àwọn olórí ní àwùjọ

Lójú Màràdónà ìhùwàsí àwọn olórí ní àwùjọ ló fa ogun ọ̀ràn dídá. Nígbà tí ó ń bá Abẹ́rẹ́ tí ó gbàgbọ́ pé owó ẹ̀jẹ̀ ni àwọn adigunjalè ń ná sọ̀rọ̀, ó ní:

> Ṣùgbọ́n bí a bá wò ó, kò sí ẹbi wa nínú iṣẹ́ tí a ń ṣe yìí. Àwọn olórí wa ń jayé láìbìkítà. A tiẹ̀ gbọ́ tàwa tí a ò kàwé jìnà. Àwọn tó kàwé ò ríṣẹ́. Wọ́n ń gun mọ́tò bọ̀lùkù kiri ìgboro. Alùfáà ń yọkùn, ọmọ ìjọ ń rù! Àwọn olódodo ìlú ń gbẹ, àwọn aláìṣòdodo ń sanra. Ìrẹ́jẹ àti ìjẹkújẹ jọba láwùjọ wa. O wá ní kí àwa kan má jalè? Àwa nìkan kọ́ ló ń náwó ẹ̀jẹ̀ bó ò bá mọ̀. Àwọn olóṣèlú wa ńkọ́? Ọ̀pọ̀lọpọ̀ wọn a rán jàndùkú sílé alátakò. Bí alátakò bá kú tán, wọn a wọlé wọ́ọ́rọ́ (*Oorun*:104-105).

Màràdónà tipasẹ̀ èrò rẹ̀ yìí fàáké kọ́rí pé òun kò lè fi iṣẹ́ ìdigunjalè sílẹ̀. Ó gbàgbọ́ pé àbákú laṣọ awo ni iṣẹ́ náà jẹ́ fóun. Bí a bá wo ohun tí Màràdónà sọ dáradára, a lè rí òótọ́ níbẹ̀ bí àpẹẹrẹ ọ̀pọ̀ olóṣèlú ni ọwọ́ wọn kò mọ́. Àkọlé kan lára àwọn àkọlé inú ìwé ìròyìn tí Ọ̀ṣúnlẹ́yẹ fi han DIG Ìdòwú ló ti kà nípa olóṣèlú kan tó fẹ́ díje sí ipò gómìnà tí wọ́n yìnbọn pa nínú ṣọ́ọ̀ṣì (*Oko*:93). Dájúdájú, kì í ṣe adigunjalè ló pa olóṣelú náà bíkòṣe agbanipa. Ìwé ìròyìn kò sọ pé wọ́n jalè nínú ṣọ́ọ̀ṣì náà. Bí ìwádìí bá tẹ̀ síwájú, kò níí ya ni lẹ́nu láti gbọ́ pé ìjà olóṣèlú sí olóṣèlú ló wáyé. Bákan náà, ọ̀pọ̀ adigunjalè ló sọ nígbà tí ọwọ́ ṣìkun ọlọ́pàá tẹ̀ wọ́n pé àíríṣẹ́ṣe ló sún wọn dédìí olè jíjà bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé orí bíbẹ́ kì í ṣe oògun iná orí. Ṣùgbọ́n bí a bá wò ó dáradára, a ó rí i pé kì í ṣe gbogbo adigunjalè ni àìríṣẹ́

sún dé ìdigunjalè. Jímọ̀ ti bẹ̀rẹ̀ olè láti ilé-ẹ̀kọ́ alákọ̀ọ́bẹ̀rẹ̀ (*Oorun*:94). Fọga ni Kúnlé Olúsọjí kí ó tó lọ dara pọ̀ mọ́ ẹgbẹ́ olè àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ.

## Ìhùwàsí Àwọn Ọlọ́pàá

Òǹkọ̀wé fi hàn pé ìhùwàsí ọ̀pọ̀ ọlọ́pàá ló ta ko àláàfìà àwùjọ. Àwọn ni wọ́n ń pe olè wá jà àwọn ni yóò sì tún pe olóko wá mú un. Màràdónà ṣàlàyé pé ó lé ní ọgbọ̀n ọlọ́pàá tí Kọ́lá Àlàó ń sanwó oṣù fún (*Oorun*:106). Èyí ni kò ṣe rọrùn fún àwọn ọlọ́pàá láti mú un. Abẹ́rẹ́ pe ọlọ́pàá ni oríṣiríṣi orúkọ nipasẹ̀ ìwà wọn, ó ní "Ọlọ́pàá! Oníṣekúṣe, onígbàkúgbà, oníjẹkújẹ, òpọnmiòkèrútodò, Alágàbàgebè, Alọnilọ́wọ́gbà, Aṣekúpani, Onírìbá, Oníró̩, Abániwọ́rànbáòrídá, Akógbósínilápò, Wọ̀bìà-wọ̀nbílíkí, Ojo, Panipani, Gbanigbani, Olè-tíímẹṣẹ̀-olè-lórí-omi" (*Oorun*:106).

Ìjọba ni àwọn ará ìlú ń dẹbi fún fún ìwàkuwà tí àwọn ọlọ́pàá ń hù; wọ́n ní owó oṣù ọlọ́pàá kéré. Abẹ́rẹ́ fìdí èrò yìí múlẹ̀ nígbà tí ó sọ pé:

> Ṣùgbọ́n bí a bá wò ó, Màràdó, wọn ò lẹ́bi. Èló ni ìjọba ń san fún wọn. Owó oṣù wọn kéré púpọ̀ (*Oorun*:106).

Àwọn ọlọ́pàá fúnrawọn gbàgbọ́ pé kò sí kóríyá nínú iṣẹ́ ọlọ́pàá. Kẹ́mi fìdí èrò yìí múlẹ̀ nígbà tí ó ń bá Bùnmi sọ̀rọ̀ lórí iṣẹ́ wọn. Ó ní:

> Èmi ò kàn rí nǹkan tí a ń kú lé nínú iṣẹ́ yìí mọ́ ni. Ìwọ náà wò ó, ọdún mélòó ló dà báyìí tí àjọ ọlọ́pàá ilẹ̀ yìí ti gbé ọ ga gbẹ̀yìn? Lẹ́yìn tí a ti bá ìyá Ìdòwú ṣiṣẹ́ Ayénígbà, mo gba ìgbéga ẹ̀ẹ̀kan. Ọdún kẹ́wàá rè é. Àwọn tí kò fi ojú winá ọ̀daràn bí tiwa tí wọ́n wà lọ́ọ́fíìsì ń gba ìgbéga lóòrèkóòrè. Àbí o ò mọ̀ pé 'kúuṣẹ́' a máa mórí ẹni wú. Kí ló ń dùn nínú ẹlẹ́wọn mi tó ń wo aago ọwọ́. Kí ni ìyá Ìdòwú tó ránṣẹ́ pè wá gan-an fẹ́ gbà sí iṣẹ́ tó ṣẹ̀ṣẹ̀ ń fi arúgbó ara ṣe yìí. Lẹ́yìn ìgbéga tó ti gbà ní Ayénígbà, kò gbà míì mọ́ (*Oko*:102-103).

A ṣe àkíyèsí pé àwọn ọlọ́pàá tí wọ́n mọ iṣẹ́ wọn níṣẹ́ ló sọ̀rọ̀ nínú àyọlò òkè yìí. Àìṣe kóríyá fún wọn domi ìrẹ̀wẹ̀sì sí wọn lọ́kàn, síbẹ̀, wọ́n fi ìrọ́jú ṣe iṣẹ́ wọn bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé kò yẹ kó rí bẹ́ẹ̀. A kò lérò pé ó yẹ kí ènìyàn ṣe iṣẹ́ erin kó máa jẹ ìjẹ èlírí. A tún ṣe àkíyèsí pé ohun tí ó ṣẹlẹ̀ sí ìṣọ̀wọ́ àwọn ọlọ́pàá yìí ti wọn ń mú un mọ́ra ni àwọn ìṣọ̀wọ́ mìíràn nínú àwọn ọlọ́pàá kò lè mú mọ́ra tí wọ́n fi sọ ara wọn di ọmọṣẹ́ àwọn ọ̀daràn, tí wọ́n ń gbowó oṣù lọ́wọ́ Kọ́lá tí wọ́n mọ̀ pé ó jẹ́ olè (*Oorun*:106). Àwọn kan lára àwọn ọlọ́pàá náà ló sọra wọn di olófòófó fún àwọn òlóṣèlú gẹ́gẹ́ bí a ti gbọ́ lẹ́nu gómìnà nígbà tí ó sọ pé:

> Àwọn ọlọ́pàá tí ó ń ṣiṣẹ́ fún mi lágọ̀ọ́ wọn ló jẹ́ kí n mọ̀ pé wọ́n ti ń tu àṣírí o (*Oko*:125).

Ìṣọ̀wọ́ ọlọ́pàá méjì ni ohun tí gómìnà sọ yìí tọ́ka sí; bí àwọn ọlọ́pàá kan ti mú àwọn tí gómìnà rán níṣẹ́ ibi ni àwọn ọlọ́pàá kan sọ ara wọn di olófòófó fún gómìnà (*Oko*:125). Kọmíṣọ́nnà pé irúfẹ́ àwọn ọlọ́pàá wọ̀nyí ní ọmọ ọsàn tó ń kó pọ́ńpọ́ bá ìyá, òbu láàrin iyọ̀, àwọn tí wọ́n ń ba ọlọ́pàá jẹ́. Níwọ̀n bí ó ti jẹ́ pé Kọ́lá Àlàó ni àwọn ọlọ́pàá wọ̀nyí ń ṣiṣẹ́ fún, yóò ṣòro fún wọn láti fi páńpẹ́ ọba gbé Kọ́lá Àlàó àti àwọn ọmọ iṣẹ́ rẹ̀. Irúfẹ́ ìhùwàsí àwọn ọlọ́pàá yìí yóò máa mú kí ọ̀ràn dídá gbìlẹ̀ ní àwùjọ. Òǹkọ̀wé bu ẹnu àtẹ́ lu irúfẹ́ ìwà bẹ́ẹ̀ ó sì mú kí àṣírí wọn tú.

## Ọ̀nà Àbáyọ sí Ogun Ọ̀ràn Dídá gẹ́gẹ́ bí ó ṣe hàn nínú Ìwé Ìtàn-àròsọ *Oorun Orí Kẹ̀kẹ́* àti *Oko Aga* Níní ohun-èlò tó péye

Òǹkọ̀wé fi hàn pé a kò lè fọwọ́ rọ́ ohun-èlò sẹ́yìn lọ́nà àtijà ogun ọ̀ràn dídá. Ojú ìwé kẹtàlélógójì ìwé ìtàn-àròsọ *Oorun Orí Kẹ̀kẹ́* ni òǹkọ̀wé ti jẹ́ kí á mọ̀ pé bí ọlọ́pàá kò bá ní ohun-èlò tó péye àtigbógun ti àwọn ọ̀daràn kò lè rọrùn. Kọmíṣọ́nnà Idòwú mọ èyí ló jẹ́ kí ó ṣètò àwọn ohun èlò tí ó lè gbé iṣẹ́ ọlọ́pàá yọ fún wọn gẹ́gẹ́ bí a ti rí i nígbà tí ó ń bá àwọn ọlọ́pàá sọ̀rọ̀ tí ó ní:

> Mo ti bá ọlọ́lá gómìnà sọ̀rọ̀, ó sì ti ṣe ìlérí láti fún wa ní ọkọ̀ ayọ́kẹ́lẹ́ tuntun márùn-ún. Àwọn ọkọ̀ náà yóò ran iṣẹ́ wa lọ́wọ́. Ẹ ò ní lo ọ̀kọ̀ọ̀-kan nínú àwọn ọkọ̀ ọlọ́pàá tí wọ́n ń túnṣe lọ́wọ́. Mo ń rétí ọkọ̀ jeep méjì láti Àbújá.Títí ọ̀la, a óò gbà wọ́n. Ìyẹn náà yóò ràn wá lọ́wọ́ nínú iṣẹ́ náà (Oorun:43)

A lérò pé Kọmíṣọ́nnà yìí kò fẹ́ ọkọ̀ tí wọ́n ń túnṣe ní pàjáwìrì nítorí ó ṣe é ṣe kí iṣẹ́ rẹ̀ máà pé mọ́, ó sì lè dá wọn dúró lẹ́nu iṣẹ́ wọn. Bákan náà, nínú *Oko Aga*, DIG Ìdòwú jẹ́ kí Ọṣúnlẹ́yẹ, ọ̀gá rẹ̀ mọ̀ pé ojú ogun gidi ni ẹni tí yóò bá mú ọ̀daràn wà nígbà tí ó sọ pé "Ṣùgbọ́n ẹ mọ̀ pé ológbò tí yóò peku asín gbọ́dọ̀ múra ìjà" (*Oko:*95). Ìdòwú jẹ́ kí ó yé ọ̀gá rẹ̀ pé ohun ìjà tí òun máa nílò kì í ṣe àwọn ìbọn ṣakabùlà tí àwọn ènìyàn wọn ń lò. Èyí fi hàn pé àwọn ọlọ́pàá gbọ́dọ̀ ní ohun ìjà ìgbàlódé kí wọ́n tó lè dojú kọ ogun ọ̀ràn dídá tí àwọn ọ̀daràn gbé ti àwùjọ òde-òní. Oríṣìíríṣìí àṣíborí, àwọn aṣọ agbọtadànù àti àwọn bàtà onípátákò erin ni àjọ ọlọ́pàá pèsè fún àwọn ọlọ́pàá kògbérèégbè. Òǹkọ̀wé fìdí rẹ̀ múlẹ̀ pé àdúrà gbígbà jẹ́ ohun-èlò pàtàkì tí ènìyàn lè fi jagun ọ̀daràn. Lára ohun-èlò tí DIG Ìdòwú béèrè lọ́wọ́ ọ̀gá rẹ̀ ni àdúrà nítorí àdúrà níí gbà, agbára kì í gbà (*Oko*:96).

Àwọn ilé ìfowópamọ́ náà nílò ohun-èlò ìgbàlódé. DIG Ìdòwú sọ fún àwọn ọ̀gá àgbà ilé-ìfowópamọ́ kọ̀ọ̀kan láti ri ẹ̀rọ atúnifó tí yóò jẹ́ kí ọlọ́pàá lè pèsè àbò tí ó péye bí àwọn adigunjalè bá dé mọ́lẹ̀ sí kọ̀rọ̀ kan nínú ọgbà wọn. Ìlò ẹ̀rọ yìí mú kí ó rọrùn fún CSP Adétúnjí láti máa wo bí kátàkárà ṣe ń lọ ní àwọn

ilé-ìfowópamọ́ gbogbo tí ó ní ẹ̀rọ náà (*Oko*:100). Mẹ́talọ́kan ni ẹ̀rọ ìbánisọ̀rọ̀ tí CSP Adétúnjí ń lò; ó jẹ́ ẹ̀rọ ìbánisọ̀rọ̀, ìbọn ìléwọ́, bẹ́ẹ̀ ni ó fún un ní àǹfààní láti rí ẹlòmìíràn tí ó gbé irúfẹ́ ẹ̀rọ bẹ́ẹ̀ dáni níbi tí ó bá wà. Òǹkọ̀wé tún pe àkíyèsí àwùjọ sí pàtàkì ìdánilẹ́kọ̀ọ́ òòrèkóòrè fún àwọn ọlọ́pàá. CP Òjòpabàtá fi odiidi ọjọ kan kọ́ àwọn ọlọ́pàá Kògbérèégbè ní bi wọn yóò ṣe lò ìbọn tuntun gbẹ̀ǹgbẹ̀ tí àjọ ọlọ́pàá ṣẹ̀ṣẹ̀ kó fún wọn. Lára àwọn ohun èlò tí àjọ ọlọ́pàá pèsè fún àwọn ọlọ́pàá ni àwọn ọkọ̀ jíípù tuntun méjọ. Àwọn ọlọ́pàá Kògbérèégbè náà kò nísẹ́ méjì ju kí wọ́n jí kí wọ́n ṣeré ìdárayá lóríṣíríṣi, kí wọn tó káàkiri. Bí àwọn ilé-ìfowópamọ́ bá sì ṣíwọ́, wọn a padà sí ọgbà wọn. Ìlò ohun èlò ìgbàlódé wọ̀nyí ló mú àṣeyọrí bá iṣẹ́ DIG Ìdòwú àti àwọn ọmọlẹ́yìn rẹ̀. Kámẹ́rà tí ó wà lára bẹ́lítì àti táì Kọ́lá jẹ́ kí àwọn ọ̀gá ọlọ́pàá mọ bí gómìnà ṣe ń fi ẹ̀jẹ̀ ọmọ tuntun wẹrí, nínú rẹ̀ náà ni a ti rí irúfẹ́ ikú tí ó pa Kọ́lá (*Oko*:126)

Yàtọ̀ sí ohun-èlò, òǹkọ̀wé tún pe àkíyèsí àwùjọ sí àwọn ohun àmúyẹ fún ọlọ́pàá lẹ́nu iṣẹ́. O fi èyí sẹ́nu Kọmíṣọ́nnà Ìdòwú nígbà tí onítọ̀hún ń bá àwọn ọlọ́pàá abẹ́ rẹ̀ sọ̀rọ̀. Kọmíṣọ́nnà kìlọ̀ fún àwọn ọlọ́pàá kí wọ́n máṣe gba rìbá, kí wọ́n gbọ́n ṣáṣá bí ejò, kí wọ́n ṣoro bí agbọ́n, bí oyin àti bí àkéeke. Ó ní wọ́n gbọ́dọ̀ já fáfá bí idì, kí wọ́n yára láti gbọ́ ṣùgbọ́n kí wọ́n lọ́ra láti fèsì. Kí wọ́n jẹ́ kí ojú wọn ṣiṣẹ́ bí tàwọ̀dì òkè bẹ́ẹ̀ sì ni bátìrì fóònù wọn kò gbọ́dọ̀ kú. Parípari rẹ̀ ni pé kò sí ọ̀gá bẹ́ẹ̀ ni kò sí ọmọ iṣẹ́ láàrin wọn títí wọn ó fi ṣe àṣeyọrí (*Oorun*: 43). Bí a bá wo àwọn ìmọ̀ràn tí Kọmíṣọ́nnà fún àwọn ọlọ́pàá yìí a ó rí i pé wọ́n wà lára òpó tí wọ́n gbé àṣeyọrí wọn lé. Bí wọ́n kò bá gbọ̀jẹ̀gẹ́ lẹ́nu iṣẹ́ tí wọ́n ń rí ara wọn pè lóòrèkóòrè tí iṣẹ́ dẹ́lẹ̀ tí ọgá kò sọ pé ó dìgbà tí ọmọ iṣẹ́ bá dé tí ọ̀daràn kò lọ mọ́ wọ́n lọ́wọ́, ó dájú pé ìṣẹ́gun yóò jẹ́ tiwọn.

Gbogbo ènìyàn ló gbọ́dọ̀ kíyèsí ohun àyíká wọn. Bùnmi sọ fún Kẹ́mi pé gbogbo nǹkan tí wọ́n bá rí ni wọ́n gbọ́dọ̀ kà sí. Ó ṣàlàyé pé ènìyàn ni àwọn ọ̀daràn, àwùjọ wa ni wọ́n sì ń gbé. Wọn ki í ṣe àpàjá tí ẹnikẹ́ni kò mọ ibi tí ó ti ń wá tàbí tí ó balẹ̀ sí. Nítorí náà, ó gbàgbọ́ pé kò sí nǹkan tí kò lè ṣe atọ́kùn wọn (*Oko*: 102). Ara kíkíyèsí ohun àyíká wọn ló mú kí Bùnmi àti Kẹ́mi gbé Oríyọmí sínú ọkọ̀ wọn; ẹni tí ó wá padà ṣe atọ́nà wọn dé ibùba àwọn ọ̀daràn (*Oko*:104-116). Kíkíyèsí àyíká náà ló mú kí àwọn ọlọ́pààbìnrin náà fura sí obìnrin ọlọ́mọ méjì tí wọ́n gbé lọ́nà Arọ̀lọ́jà tí wọ́n fi rí i pé ọ̀kan lára àwọn gbọ́mọgbọ́mọ ni (*Oko*:106).

## Àgbálọgbábọ̀

Nínú iṣẹ́ yìí, a ti fìdí rẹ̀ múlẹ̀ pé ìwé ìtàn-arosọ̀ ajẹmọ́ ọ̀ràn dídá ni Olúmúyìwá kọ nítorí pé bí kán-ún já ìlasa ni ìwà ọ̀daràn kún inú ìwé náà fọ́fọ́. Onírúurú ogun ọ̀ràn dídá bí i ìdigunjalè, ìfiniṣètùtù, ìfipábánilò, ìjínigbé, ìpànìyàn, ìlò bọ́ǹbù àti ohun ìjà olóró mìíràn tó ń fa àìbalẹ̀ ọkàn ló kún àwùjọ gẹ́gẹ́ bí ó ti

hàn nínú àwọn ìwé ìtàn-àròsọ Yorùbá tí a yẹ̀ wò. Lára ohun tí òǹkọ̀wé fúnka mọ́ pé ó ń fa ogun ọ̀ràn dídá ni àìsíṣẹ́ fáwọn ọ̀dọ́, àìní ìtọ́jú láti ọ̀dọ̀ òbí, wíwọ ẹgbẹ́ òkùnkùn àti àìní ìtẹ́lọ́rùn. A sì tún fi hàn pé bí ìlú yóò bá sì tòrò, a nílá-ti dojú ogun kọ àwọn ogun wọ̀nyí nípa ṣíṣe kóríyá fún àwọn ọlọ́pàá bí pípèsè ohun-èlò ìgbàlódé, ìgbéga lásíkò àti owó oṣù tó jọjú. Àwọn ọlọ́pàá sì nílati jẹ́ olóòótọ́ nínú iṣẹ́ wọn. Bákàn náà, kí òbí kọ̀ọ̀kan bojú tó ọmọ rẹ̀, kí ìjọba gbìyàn-jú láti pèsè iṣẹ́ fún àwọn ọ̀dọ́ láti mú kí àdínkù bá ogun ọ̀ràn dídá tó ń ja àwùjọ.

## ÌWÉ ÌTỌ́KASÍ


Abéjidé, (2016). "Representations of Crime in Selected Novels of D.O. Fágúnwà", nínú Adébọ̀wálé, O., Adélékè, D., àti Adéjùmọ̀, A. (Olóòtú) *Ọ̀tun Ìmọ̀ nínú Ìtàn-Àròsọ D.O. Fágúnwà*, pp. 186-195.

Adébọ̀wálé, O. (1995). "The Detective in Yorùbá Crime Fiction", *Ọlọ́ta*: Journal of African Studies, vol.1, No. 1, o.i pp.60-68.

Adébọ̀wálé, O. (1999). *Ọgbọ́n Òǹkọ̀wé Alátinúdá*. Lagos: The Capstone Publications.

Adébọ̀wálé, O. (2003). "Ìṣọwọ́lo-èdè II", Mimeo.

Adéoyè, C.L (1979). *Àṣà Àti Ìṣe Yorùbá*, London: Oxford University Press.

Adéyẹmí, L. (2002). "Lítíréṣọ̀ Yorùbá àti Ọrọ̀-ajé Nàìjíríà", Pépà tí a kà níbi Àpérò Ọlọ́dọọdúnti Ẹgbẹ́ Onímọ Èdè tí ò wayé ní Yunifásitì Ado-Èkìtì, Ìpínlẹ̀ Èkìtì.

Dáramọ́lá, O. Àti A. Jéjé (2005). Àwọn Àṣà àti Òrìṣà Ilẹ̀ Yorùbá, Ìbàdàn: Oníbọn-Òjé Press.

Fágúnwà, D.O. (2005). *Igbó Olódùmarè*, Ìbàdàn: Nelson Publishers Limited.

Irene, M.P. (2017). Animal Language Studies: What Happened? https://link.springer.com.article

Ìṣọ̀lá, A, (1998). *The Modern Yorùbá Novel: An Analysis of the Writer's Art*, Ìbàdàn: Heinemann

Olúmúyìwá, O.T. (2008). *Oorun Orí Kẹ̀kẹ́*, Lagos: The Capstone Publications.

Olúmúyìwá, O.T. (2012). *Oko Aga*, Àkúrẹ́: Montem Paperbacks.

Ògúnṣínà, B. (1991). Ìdìde àti Ìdàgbásókè Ìwé Ìtàn-Àrò*sọ Yorùbá*, Ìlọrin: Yunifásítì Ìlọrin.

Ògúnṣínà, B. (1992). *The Development of the Yorùbá Novel 1930-1975*, Ìbàdàn: Gospel Faith Mission.

Ọ̀pẹ́fèyítìmí, A. (2014). *Tíọ́rì àti Ìṣọwọ́lo-èdè*, Ọbáfẹ́mi Awólọ́wọ̀ University Press, Ilé-Ifẹ̀